Bibeli fun awon omode

# Dafidi Omokunrin Oluso agutan



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Ni igba kan, ni igba aye Oba Soolu ni ile Israeli, Omodekunrin kan ti oruko re n je Dafidi n ba awon egbon re so agbo eran baba won.  Lati kekere ni Dafidi ti je eni to lagbara, ologbon ati eni to ni ife ti o si gba Olorun gbo.  Oun si n gbe ni Betilehemu.



Kinnihun kan si wa, o si gbe odo agutan kan lati inu agbo lati paje.  Omodekunrin Dafidi naa si jade too, o si lu u o gba odo agutan naa kuro lenu re, O gba Irungbon re mu, o si lu u, O si paa.  Dafidi si mo pe Oluwa wa wa pelu oun.



Samueli, wolii Olorun, inu re baje gidigidi si Oba Soolu nitori ti oun ti re ofin Oluwa koja ati oro re, Oluwa si wi fun Samueli pe yoo ti pe to ti Iwo o fi maa sofoo Soolu? Emi o ran o lo si Jese... nitori ti emi ti pese Oba kan fun ara mi ninu awon Omo re. Jese si ni baba Dafidi.



Koda gan-an Samueli mo pe ti Soolu Oba ba gbo pe oun n wa Oba miiran lo, Soolu Oba yoo pa Oun.  Samueli si se eyi ti Oluwa wi.





Nigba ti Samueli de, Jese mu ki gbogbo awon Omokunrin re mejeeje koja niwaju Samueli. Samueli si wi fun Jese pe Oluwa ko yan awon wonyi.  Abikeyin won ni o ku, O n so agutan. Won si mu Dafidi wole, Oluwa si wi fun Samueli pe 'Dide' ki o si fi ororo sa a ni ami, nitori pe oun naa ni eyi.

Ni aafin Soolu, Emi Olorun fi Soolu sile, emi buburu si n yo o ni enu.  Awon iranse Soolu ro o lati wa Okunrin kan ti o mo duuru ifi korin lati je ki okan soolu bale okan ninu won mo arakunrin kan ti o le fi duuru korin daradara. N je o mo eni ti arakunrin naa n se? beeni Dafidi ni.



Orin Dafidi si mu Soolu larada, oun si ran-an-lowo lati je ko ronu siwaju sii.  Soolu si wi fun Jese pe ko je ki Dafidi duro niwaju ijoba oun.  Igbakugba ti emi buburu ba de si Soolu, Dafidi a ran-an-lowo lati fi owo re korin lara duuru fun-un.



Leyin ti Dafidi lo si ile tan, Ogun awon ara Filistini dide si Soolu, awon egbon Dafidi meteeta si to Soolu leyin lo si oju ija.  Jese si ran Dafidi lo si oju ija lati mu ounje lo fun awon egbon re ki o si wo bi awon egbon re ti n se.



Akikanju Okunrin Filistini, Oruko re n je Golayaati.
Eru nlanla si ba awon Omo ogun Israeli.



Golayaati si kigbe. Eyin yan Okunrin kan fun ara yin, ki eyin si je ki o sokale to mi wa. Bi oun ba le bami ja, ki o si pa mi, nigba naa awa o di eru yin. Sugbon bi emi ba si pa a, nigba naa ni eyin o di eru wa, eyin o si maa sin wa. Nigba ti gbogbo Israeli ri akikanju Okunrin Filistini yii, eru nlanla si ba won.



Nigba naa ni Dafidi so fun Soolu wi pe 'ki aya ki o ma se fo enikeni nitori re, iranse re yoo lo yoo si ba Filistini yii ja. Sugbon Soolu fe fi gbogbo Ihamora ogun re wo Dafidi pelu ida. Dipo Ihamora, Dafidi towo bo apo re, o si Sa Okuta marun-un ti o jolo ninu odo.



Nigba ti Golayaati si wo ti o si ri Dafidi, o rerin-in, nitori pe Odomodekunrin nii se koda ko tun wo Ihamora ogun.  Oun si ke ni ohun rara pe emi o fi eran ara re fun awon eye oju orun, ati fun awon eranko papa. Dafidi si da a lohun pe lonii yii ni Oluwa yoo fi iwo lemi lowo... nitori pe ogun naa, ti Oluwa ni.





Dafidi si yara, O si sure si Ogun lati pade Golayaati. Dafidi fi owo re sinu apo, o si mu okuta kan lati ibe wa, okuta naa si wo inu agbari Golayaati lo.  Golayaati si subu yakata.

Dafidi si sare, o duro lori Golayaati naa, O si mu ida re, o si fi ida naa be ni ori. Nigba ti awon Filistini si ri pe Golayaati ku, won si sa fun emi won.





Soolu Oba ko ranti pe Dafidi kan naa to n fi owo re korin lara duuru fun oun ni. O si fi je olori ogun. Soolu si n se ilara Dafidi nigba ti gbogbo eniyan n yin in fun aseyori re. Soolu n ro pe kin ni o si ku fun-un bi ko se ijoba. Oju Soolu si wa lara Dafidi lati ojo naa lo.



O si se, ti emi buburu kan ba le Soolu, nigba naa ni Dafidi tun fi owo korin lara duuru fun-un.  Soolu ju ida si Dafidi lemeeta.  Dafidi si sa kuro niwaju re,



Eru Dafidi si ba Soolu nitori pe oun ti mo pe Oluwa wa pelu re, sugbon oun sa kuro niwaju Soolu Oba.



Sugbon Jonataani omo Soolu feran Dafidi pupo "Soolu baba mi n wa ona ati pa O," O si kilo fun Dafidi, Dafidi si salo. Aya re si mu ere, O si te e sori ibusun re, Oun si so Dafidi kale lati oju ferese ni aarin oru. Nigba ti awon eniyan Soolu de ni owuro. Dafidi ti lo.



Dafidi ni lati sa lo kuro lodo Soolu, ki o to se e Oun ati Jonatani da majemu pe awon o maa ran ara awon lowo nigbogbo igba. Awon ore meji dagbere pelu ibanuje, Dafidi si wa ibi ti yoo maa gbe laisi iberu awon omo ogun Soolu.



Dafidi Omokunrin Oluso agutan

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Samueli kin-in ori kerindinlogun
titi de ori ogun

“Iwole oro re funwa ni imole.”
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.